# *Idagbasoke*

AWON OBIRIN ATI AWON OMODE

**Ipo Awon Omode Agbaye ni Odun 200** **9mins. 26secs.** **3**
*Ajo UNICEF to awon orile-ede Afirika siwaju ninu awon to ti fi awon anfaani lati mu awon omode won dagbasoke sofo.*

**'Bi o se ri ki eniyan ma ni ireti'** **11mins. 22secs.** **5**
*Ncele Kgadima, ti a ju sewon fun ese itiraka lati pa ikoko, se ifojusi bi o se ye lati se agbeyewo osi ati eko fun awon obirin.*

**Awon Obirin na se pataki** **10mins.** **6**
*Awon eto awon omode ni a ti sopo pelu ilera ati iwalalafia awon iya.*

**Leyin Awon Omode Na** **3mins. 29secs.** **10**
*Ile-ise Ajo Agbaye fun Awon Asasala Ogun ati Ajo Alasepo lori Akojo Owo fun Igbala Awon Omode ti gbe eto ise kale lati se iranlowo fun awon omode ti a ko sile to nwa ibugbe ni ile Europe.*

AWON AJO IROYIN

**Iyipada Rere ati Awon Ajo Iroyin** **4mins. 50secs.** **9**
*Aare Egbe Awon Onise Iroyin ni Iwo-Oorun Afirika ti kilo fun awon onise iroyin wipe ki won mase jeki ifitorese nipa lori ibalopo won pelu ijoba.*

**Awon ti a da lola Nobel soro lori ominira Ise Iroyin** **3mins. 16secs.** **9**
*Awon meji ti a da lola Nobel, Dalai Lama ati Bharat Ratan Amartya Sen, ro awon onise iroyin lati se ayipada awujo ki won si se ifojusi ero tooro lati se iranwo lati so gbogbo agbaye di abule kansoso.*

ILERA

**Rawlings di Agbenuso Ajo Agbaye lori Iyonda-ara-eni-fun-ise** **5mins. 39secs.** **9**
*Aare orile-ede Ghana tele, Jerry Rawlings, ni a fi se Eni Pataki Ajo Agbaye fun Iyonda-ara-eni-fun-ise latari ikun ojuiwon ati ifaraji re to jinle si awon oran ilera to se koko.*

ORO AJE

**Ajo UNDP kepe fun ona Iselatiberepepe fun Idinku Osi** **11mins. 57secs.** **4**
*Ajo UNDP so wipe idinku osi ni a gbodo koju lati iha ti eda eniyan ati ti agbaye.*

**Ile Afirika ninu Igbimo Aabo Ajo Agbaye?** **8mins. 22secs.** **11**
*Ifikunlukun lori atunse to jinle ninu Ajo Agbaye.*

# *Ayika*

IDOTI

**Irokeke Ewu ti a ko le fi oju ri wa ni Muizenberg** **10mins. 27secs.** **3**
*Ise Agbese kan ti orile-ede South Africa ti nse apejuwe re bi "emi imo ero" le ba afefe je pelu eefin alagbara chlorine.*

AFEFE ILE

**Iyipada Afefe Ile yio na ni lowo to to Odunrun Bilionu owo Dola Amerika lodoodun.** **6mins. 16secs.** **8**
*O seese ki imorusi aye ni agbaye na ni opolopo bilionu owo dola Amerika lodoodun ayafi ti a ba gbe igbese ni kiakia lati dekun itujade awon eefin alagbara to nba ayika je.*

ITOJU

**Itoju Ayika lo sinu Fiimu** **6mins. 27secs.** **10**
*Fiimu ti Elaine Proctor sese se ti a pe ni 'Kin' topinpin itakorawon to wa laarin itoju ati eto agbegbe, o si se ayewo imuwalalafia awon eya ni orile-ede Namibia.*

## *Bi mo se rii si*

**Idajo Ododo fun Awon Omode Orile-ede Saro** **10mins. 40secs.** **11**
*Igbimo Ajo Agbaye pari ise lori ipa ti orile-ede Liberia ko ninu egbe alafowosowopo lori pasipaaro okuta iyebiye dayamondi fun ibon eyiti o nfa iha iwo-oorun ile Afirika ya. Kini igbese to kan?*

## *A ti gbo*

**Orile-ede Algeria gba awon Ile-Olomi titun** **2mins. 33secs.** **12**
*Orile-ede Algeria ti se akosile awon ile olomi titun mewa to se pataki kariaye isaami Ojo Ile Olomi ni Agbaye.*

**Omodekunrin kan to nsaisan lile latari Arun Kogboogun Eedi di omo odun mejila** **3mins. 6secs.** **13**
*Ajafitafita lori Arun Kogboogun Eedi ti ojo ori re kere ju ni orile-ede South Africa, Nkosi Johnson, to sese pe omo odun mejila si wa lori idaku olojogbooro.*

## *Eto Awon Omode*

**Kumbo ati Mhisi** **12mins. 7secs.** **13**
*Kunbo olorikunkun padanu emi re sowo akata to nje Mhisi latari aigboran si awon obi re.*

## *Awon Oro Asokagba*

*Awon oro manigbagbe die ti awon olori Ile Afirika so ati oro lori itumo gidi fun ewa.* **14**

# *Iroyin*

**Ipo Awon Omode Agbaye ni Odun 2001** **9mins. 26secs.**

Awon orile-ede Afirika lo wa niwaju ninu awon orile-ede to ti fi awon anfaani lati mu awon omode won dagbasoke sofo latari awon eto imulo to nfi nkan sofo, awon ogun ti ki nidi ati jiji awon oro orile-ede. Ajalu ifi anfaani sofo yi ni o je koko pataki iroyin ti Ajo Akojo Owo ni Agbaye fun Awon Omode (United Nations Children's Fund (UNICEF) sese gbe jade. Iroyin na ti a pe ni "Ipo ti Awon Omode Agbaye wa ni Odun 2001 ni o to awon orile-ede aye leralera gegebi itesiwaju ti won ti ni lati koju awon ojuse won si awon omode, eyiti won faramo ninu ipade agbaye lori awon omode ni odun 1990.

Carol Bellamy to je olori ajo fun awon omode na so ninu iroyin na wipe "idoko owo ninu idagbasoke ati itoju awon omo wa to kere ju ni o je iru ije olori rere to sekoko julo." Ninu iroyin na, o so wipe titu agbara ogbon ori awon omo sile nipa awon idoko-owo to munadoko ninu ilera, eko, ounje to peye, itoju omo ati idaabobo ki ise ohun ti o kanpa ti o si tona nikan sugbon o tun je oro-aje to mu ogbon dani ti o gbodo sele ni iberepepe igbesiaye omode. Gegebi o se so, "Ajalu to buru julo ni wipe opolopo awon to nse ipinnu ni ko mo bawo ni awon odun meta to siwaju ninu igbesi aye se se koko to - osi ni igba omode kan de ekeji, lati okan kan de ekeji o ma nyorisi ipadami agbara eda eniyan."

Awon orile-ede Afirika to wa labe asale Sahara lo jebi ju ninu oran yi, nitori won nto awon ekun aye to ku leyin, won ko si de oju iwontunwonsi ninu gbogbo eka ti won to sile. Ile Afirika lo siwaju ninu awon isiro osi, rogbodiyan ati kokoro-arun HIV ati Arun Kogboogun Eedi ti o si ti da gbogbo aseyege to ti watele ninu igbelaruge itoju awon omode pada seyin. Ile Afirika lo ni eyi to poju ninu awon eniyan bi ogoji milionu ti rogbodiyan ati eto eda eniyan to si nipo pada labe-ile pelu bi awon eniyan bi milionu mefa ati edegberin ole adoota egberun to sipo pada ni orile-ede Sudan Angola, Burundi ati Angola.

Ninu oran eko, awon isiro elekunjekun ti Ajo Agbaye fun Oran Eko, Imo Ijinle Sayensi ati Asa Ibile (U.N. Educational, Scientific and Cultural Organisation (UNESCO) fihan wipe iko marundinlogota ninu ogorun ni iwontunwonsi ni ile Afirika to wa labe asale Sahara ko ni afiwe iko metalelogorin ni Aaringbungbun Ila-oorun, ati Ariwa Ile Afirika, iko mokanleladorin ni Gusu Ile Asia, iko merindinlogorun ati aabo ni Ila-oorun Ile Asia ati Pacific, iko mokandinlogorun ati aabo ni Latin Amerika ati Caribbean ati iko mokanleladorun ni Aringbungbun ati Ila-oorun Ile Europe ati awon orile-ede Baltic.

Sugbon ohun to dabi enipe o buru julo ninu gbogbo re ni awon milionu milionu omode to ti di omo orukan latari Arun Kogboogun Eedi ti ojo iwaju won si ti dipa latari osi. Ni awon apakan iha gusu Afirika, bi idamewa awon omode ti ojo ori won ko to odun meedogun lo ti padanu iya won tabi obi mejeji si ajakaye-arun ti a pe ni ajalu to buru julo ni igba tiwa.
Bi ipo awon obirin ba si wa ni dogbandogba pelu ti awon omode, gegebi iroyin na se tanmo, nigbana awon omode ni iha isale asale Sahara, nibiti opolopo milionu awon obirin ti ni ikolu iwa-ipa abe-ile ati rogbodiyan, ni ona to jin lati lo ki won to le ri itesiwaju ninu itoju won.

Bi iroyin na ba se e tele, awon orile-ede Afirika si ni lati se nkan pupo sii lati mu ipo awon omode won dara sii, ki won si tipa be daabobo ojo iwaju wa.

*CFC*

**Irokeke Ewu ti a ko le foju ri wa lori Muizenberg** **10mins. 27secs.**

O seese ki ise agbese kan ti Ijoba ibile ti South Peninsula ni orile-ede South Africa polongo re bi "emi imo ero" ba afefe Cape Riviera je pelu eefin alagbara chlorine, to je okan ninu awon ayokele pani to buru julo lorile aye. Nigbati igbimo ijoba ibile na ba pade, a o gbe aba siwaju won fun idasile ile-ero fun sise ohun

elo igbalode kan ti a mo si optic fiber ninu Ogba Egan Capricorn ni ile Muizenberg. Igbimo ijoba ibile na fun ise lori aarin-ilu ati ayika na ti tanmo ayipada ninu ilo ile lati le se igbekale nkan yi ti yio se alekun ninu ise si ibikan to je iwon mita irinwo din ladota si itedo kan ti eniyan kun be faya sugbon ti ijoba ko fowo si ti o si tun wa ni irekoja titi si awon ile olowo giga ti a nko ni idojuko eti ebute. Gegebi awon alatako se so, awon itedo eda eniyan mejeji yi ni yio ni idojuko ewu ti a ko le foju ri ti o le gba won sinu okun kariaye Atlantic lati owo awon eefin alagbara hydrogen ati nitrogen eyiti a kojo sinu ibudo na ti ise agbese na ba tesiwaju.

Ohun isoro niyi fun ile Muizenberg to ti figbakan je ibi igbafe aayo fun awon Ju to wa ni Johannesburg. Ile-ise na ni yio se idasile ise titun ti o to adojo ati odunrin o din aadota ise miran to ro moo ni apa kini re ninu eyiti a ti ri ile iso to ga to aja ile mejila. Iseese itujade eefin alagbara chlorine ati ibugbamu hydrogen ni o ti da iberu sile ni agbegbe. Ijoba ekun Western Cape to ni ase lori ipinnu iyipada ilo ile, sugbon opolopo eniyan ni Muizenberg, paapa ni itedo Vygrond ti ko lowo ijoba ninu ati ti Marina da Gama to wa nitosi, ni ko mo ewu to wa ni enu-ona won lati inu ibi ti won gbagbo wipe o je “Ogba Imo Ijinle Sayensi” biotilejepe iyipada wa ninu awon eto ti won koko se kede re ninu ipade ita gbangba akoko lori oran na ni osu kejila odun to koja.

Ni odun meji seyin, awon iwadi ojutaye lori osi, eyiti Archbishop Njongonkulu Ndungawe ti ijo Anglican ni Cape Town se alaga won, bere idi re to fi je wipe awon ile-ise to ni itujade oloro ni won ma nda sile legbe itedo awon talika paraku laiko gbo tenu awon ara agbegbe. Paapa, ninu didaba atunse ti a ko pariwo re lati yi ibudo Capricorn pada kuro ni ilo gegebi agbegbe iwadi lori imo ijinle sayensi ati imo ero si “agbegbe ile-ise to ni itujade oloro”, igbimo ijoba ibile na woye wipe “ni ojo iwaju, ati nibiti o ba ti ye, ki a se imulowosi awon ara ilu, ni ona to gboro si.” Atako kansoso to nipa lowa lati odo Egbe fun Eda Abemi Egan ati Ayika ni orile-ede South Africa. Egbe na jiyan wipe iwe ebe ti won koko kowa fun iyipada ilo ile ni o je fun ile-ise “Akojopo Imo Ijinle Sayensi” ti ko ni ero alagbara ni ifegbekegbe pelu awon ile itura, ile itaja aud awon ibudo fun faaji ti won ti fowosi. Nipa yiyi awon ilana fun ilo-ile pada, egbe na so wipe ijoba ibile na ti fi awokose lele fun awon ile-ise onitujade oloro miran.

Yato si eyi, oran ti eefin alagbara chlorine “to lewu pupo” wa nile, eyiti iwadi fihan wipe afefe mimo to ni eroja re to je iko kan ninu egberun le pa eniyan. Ninu iye re to je iko mewa pere ninu milionu kan, ailera ati idaamu mimi sele leyin idaji wakati kan. Iwe emi-o-faramo ti egbe na ko so wipe “Opolopo nkan lo le mu ki itujade efin alagbara Chlorine lati inu ile-ise na sinu awon itedo to kun fun eda eniyan bi Vrygrond, fa iparun to po si agbegbe.” Bena ni itujade eefin alagbara Hydrogen to “nsare gbina to si nbugbamu” lati inu awon agba itoju to le fa ibugbamu ati ina, le yorisi iparun to buaya.

Ni tiwon awon oludasile njiyan wipe ilana igbase ohun elo igbalode Optic Fiber ntu eefin alagbara chlorine to kere pupo jade, ati wipe afefe ti yio tu jade lati ile-ise na ni a o fo mo lati yo Chlorine na kuro. Ijoba ibile na ti yan awon oludaninimoran agbegbe kan lati se iwadi apilese lori ikolu si ayika lara eyiti itopinpin gbodo waye lori itujade awon eefin alagbara chlorine, hydrogen, nitrogen ati awon ewu to wa ninu ikojopo won sinu ibudo na.

*Mail aud Guardian*

**Ajo UNDP Kepe fun ona Ise lati berepepe fun Idinku Osi** **11mins. 57 secs.**

Bi o tile je pe ifenuko wa lori awon ona pataki lati gba de ibi ifojusi ninu Ipade Egberun odun yi lati din osi to lekoko ku si idaji nigbati yio ba fi di odun 2015, igbese lati din osi ku gbodo lo koja ifojusi awon aseyori oro aje lati dojuko awon abajade osi lori eda eniyan ni agbaye. Eyi ni oro ti alase Ajo UNDP, Mark Malloch Brown so. O fere to enikan kan laarin marun - awon bilionu kan o le igba milionu okunrin, obirin ati omode - to ngbe ninu osi to lekoko, ti won nna owo to din ni owo dola Amerika kansoso loojo. Awon abajade re buru pupo.

Idamarun iye olugbe agbaye to talika ju ni o seese ni ilopo merinla lati ku ni igba ti won wa lomode ju idamarun to lowo julo laye. Brown ni "osi ati awon olomoge re to je arun ati rogbodiyan ni a ko le ge kuro lati iyoku aye" O ni won ma nsaba se danu, boya gegebi iwa odaran kariaye, awon ogun okanjuwa ati ibinu, itankale kokoro-arun HIV ati Arun kogboogun Eedi ati awon arun miran tabi ayalu awon asasala ogun ati awon awo-orile-ede lona tiko-bofin-mu lati awon orile-ede to talika julo ti won nkanlekun awon orile-ede to lowo waye. Alase ajo UNDP na so wipe "A gbodo ma ranti nigbagbogbo wipe osi koja aini owo lowo nikan, o je iduni ni eto eni, iduni ni anfaani ati iduni ni ireti fun ojo iwaju".

Gegebi o se so, awon oran agbaye meta ti a gbodo dojuko ni aidogba ninu isowo, bi o se ntokasi wipe bi owo epo robi tile lo soke ni odun to koja, owo ti a nta awon oja bi kofi, gedu ati ororo agbon lo sile pelu iko ogoji ninu ogorun tabi jube lo, eyi si ni ikolu to buru pupo lori opolopo awon orile-ede to sese ndagbasoke. Isoro na ni awon orile-ede to lowo wa nmu buru si nipa ifaseyin won lati si awon oja won sile, paapa ninu ise ogbin ati aso. Awon orile-ede to sese dagbasoke yio ni ere to to ogun bilionu owo dola Amerika lodun kan pelu imukuro awon owo iderun lori ise-ogbin nikan. Awon orile-ede to lowo lagbaye ti faramo ati mu awon idilowo to ku kuro fun, o kere tan, awon orile-ede mokandinladota to ko dagbasoke rara.

Ogbeni Brown tun kilo wipe "ohun keji ti o tun se koko pupo ni wipe a gbodo sora ki a ma jeki ife owo to nsan kakiri aye tanna si wa loju" Bi isanwole owo pupo ba wa ni odun kan, o seese ki isanjade onidagiri telee ni kiakia. Awon orile-ede to talika ni lati yi oju won si awon agbegbe ikowojo ati ifunnini eyawo abeele ti a ko kobiarasi, ki a si kobiara si sise iwuri fun ifowopamo labeele, titu owo sile ni awon agbegbe bi ile kiko ti ko lowo ijoba ninu ati mimu eto eyawo onikerejekereje gbooro sii. Lona keta, a gbodo se iwuri fun isan imo-ero lagbaye lona to yara sii si awon orile-ede to talika. Eyi to se pataki julo ninu awon wonyi, iyen imo ero nipa Ifitonileti ati Ibanisoro, ma nni agbara lati ran awon orile-ede to sese ndagbasoke lowo lati di alabasisepo kikun ninu oro-aje agbaye. Ohun to tun se pataki pupo ni alekun ise lori awon itoju fun awon arun bi ako iba, iko egbe ati kokoro-arun HIV ati Arun kogboogun Eedi eyiti o ti da ilosiwaju opolopo ewadun pada seyin ni awon orile-ede to ni ikolu julo.

Ajo UNDP to je asiwaju ajo agbaye lori osi, ndin ifojusi re ku tooro si fifunni ni imoran lori isejoba tiwantiwa, agbara isowo ati imo ero lori ifitonileti. Ajo UNDP tun nse afikun awon oran to jemo o - ti koko re je ifiagbara fun awon obinrin ati idaabobo ayika nipa awon nkan bi agbara ina alagbero - sinu igbejako osi. Itupale oran ati iparowa fun, paapa nipase awon iroyin agbaye ati ti orile-ede lori Idagbasoke Eda Eniyan ti nse pataki pupo.

Laipe yi, akowe agba fun Ajo Agbaye yan igbimo kariaye kan lati gbe aba sile lori ati ri owonna fun apero agbaye pataki kan. Aare orile-ede Mexico tele, Zedillo lo se alaga igbimo, ti Akowe Agba tele fun Ile Isura ti orile-ede Amerika, Rubin, wa lara awon omo igbimo. O seese ki awon eyi mo le itesiwaju to ti wa teletele ki won si se agbekale itage to lagbara fun idagbasoke fun egberun odun titun yi ni isopo taara pelu awon ifojusi Egberun odun. Brown so wipe: Ere rere nfe idoko-owo rere. "Bi aye ba si fi oju ojo iwaju wo oro na to si se idoko-owo na laarin awon talika agbaye, ki o si da won po pelu awon iyipada ti mo ti to sile loke yi, mo gbagbo wipe o seese fun wa lati bori ija ti a ngbeko osi".

*Pan African News Agency*

**"Ko si Eniti o mo bi o se ri ki eniyan ma ni ireti"** **11mins. 22secs.**

Ni osan ojo kan ninu osu kejila odun 1996, ni nkan bi odun merin seyin, Ncele Kgadima ti ara re mo inu salanga kan lori ile ile kan ni igberiko Ga-Maribana, Moletji, ni eyin odi Pietersburg ni ekun ariwa. Obinrin alaboyun na, omo ogun odun ni igba na, bi omo na ninu salanga to ni oorun buruku, to ni orinrin to si sokunkun. O si rin jade lo. Omo ikoko okunrin na ye. Leyin itoju die fun igbonatutu ara to lo sile pupo

ninu ile iwosan, won fi si abe itoju alagbato. Iya re ni a dalebi esun itiraka lati paniyan ati ti ihuwa lodi si Ofin Itoju Omode nipa fifi omo na sile. Ni osu kewa odun to koja leyin bi odun meta to ti se ese na, won ju Kgadima si ewon odun meta.

Ni osu kini odun 1997 ni igba akoko ti awon olopa de ile oga re ni Laudium nitosi Pretoria lati bere oro lowo re, o jewo wipe on ju omo on nu. Won mu won si fii sile leyin ti won ti gba iduro eleedegbeta Rand fun, won si ni ki o farahan ni ile ejo leyin ose meji. Sugbon leyin opolopo owo sisan ati iwo oko takisi lo si Pretoria, ejo na wo odun keji. Nigbati won sun ejo na siwaju fun igba ikeje ni odun 1998, Kgadima pinnu wipe on ki yio lo si ile-ejo mo. On ti gba wipe on jebi, nitorina kilo tun nfa idaduro. Pelupelu, gbogbo bi won se nse ni ile ejo ko yee, ko si si eniti o se aniyan lati se alaye ohunkohun fun un. Agbejoro nbaa soro nipase oga re. Nigbati ko yoju si ile-ejo ni ojo igbejo, oko awon olopa alawo buluu ati funfun de lati mu lo. Kgadima ni eto labe ofin orile-ede si igbejo ti a separi “laisi idaduro ti ko nidi”. O tun ni eto si iboyunje. Gegebi o ti wa ninu ofin Ife-inu lati ba oyun je ti odun 1996, obinrin-ko-binrin le lo si ile-iwosan ijoba ki o si bere fun iba oyun ti ko iti koja osu meta je. Sugbon lotito, awon obinrin ma ndojuko ainiye isoro lati je anfani awon eto wonyi. Awon obinrin ti ko ba mo awon anfaani to si sile fun won yio yan ona eyin nigbeyin, won a si tipa be fi emi ara won wewu nipa liko ohunkohun lati ose olomi Jeyes titi de irin igbe-aso-ko lati fi yo oyun na damu. Awon miran, gegebi Kgadima yio pari oro won sinu ewon fun itiraka lati pa ikoko won asesebi, ti won si ma nri pa nigbamiran. Oku keekeeke ti awon ikoko ti a fun pa tabi ti a fi sile lati ku ninu papo wa lori opolopo abo perese ninu ibi igbeokusi ijoba.

Ni ile ejo, agbejoro ijoba bu enu ate lu Kgadima fun iwa “aini itara ti iya” Sugbon ohun ti ile-ejo ko gbo ni igbe-aye ikosile, osi to le pupo, aini anfani eko iwe ati, paripari re, igbekuta to mu ki Kgadima gbe ikoko asesebi re sile lati ku. Iya on furarare ti o se apejuwe re bi ‘omuti kan’, fi on na sile. Kgadima lo aye re ninu titun ile awon elomiran se lati toju awon omo re keekeeke, ibatan re eleni-odun mejidinlogorin ti a mo si Rosina ati awon omo re meji, Josiah omo odun meje ati Selina, omo odun mewa.

Ni ile-ejo, agbejoro ro ile-ejo lati fi aini imo eko Ngadima si ero ati wipe o seese ki inu re baje sugbon agbejoro ti ijoba ati ile-ejo ko eleyi. O so fun Kgadima wipe “O mo wipe omo ikoko kole funrarare kuro ninu iho yen, o si seese ko ku, sibe o rin kuro nibe bi enipe ko si nkokan. Iru ona iku buruku wo ni eyi!”

Ohun to kan eniyan nipa Kgadima ni wipe o jewo ohun to se o si dabi enipe o ni ironupiwada. Sugbon nigbati awon osise ijoba pe e nigba igbejo re wipe ki o gba omo na pada, o ko. O so pelu ibanuje wipe “ko si eniti o mo bi o se ri laini owo, laini ireti bi emi se ti mo”
Oruko re gangan ko ni a lo.

*Mail and Guardian*

**Awon Obinrin Na se Pataki** **10 mins.**

Eto awon omode ko le kese jari bi a ko ba fun ilera ati alafia awon iya ni ikobiarasi to ye. Ni opolopo ona ni awon obinrin fi nkopa to nipon ninu iwalalafia awon omode, nitori idi eyi, igbelaruge ipo awon obinrin, ati ona ni dogbandogba si eko, igbeko, eyawo ati awon eto iranlowo miran je ilowosi to niyelori pupo si awon odo orile-ede. Awon obinrin to ba nsaisan nigbakugba, ti ebi ba npa, ti a ba nfiyaje ti a si nyasoto ko le ni okun, ife-inu ati iwuri lati toju awon omo won de oju aami. Apero Agbaye ti odun 1990 fun Awon Omode na jewo ifarakorawon yi laarin iya ati omo. Ise pataki imudogbba eya fun idagbasoke awujo ni a fi ese re mule ni odun 1979 nigbati Ipade Gbogboogbo ti Ajo Agbaye gba Adehun Kariaye lori Imukuro Gbogbo Ifiyasoto si si Awon Obirin wole.

Lati odun 1990, bi o se ye lati fi opin si ifiyatosi ati awon iwa miran to mu ipanilara wa fun awon obinrin gegebi ipile fun imudogbba eya, idagbasoke ati alafia ni a ti ntenumo nigbogbogba ninu awon ikede ati adehun ajo agbaye bi Apero Vienna ti odun 1993 lori Eto Eda Eniyan ati asetele ipade re to waye ni ilu

New York ni odun 2000. Pelu gbogbo eyi, lodoodun ni awon ajo UNICEF, UNIFPA, Banki Agbaye ati UNDP ngbe awon akosile isiro to banileru jade eyi to si njerisi wipe aye si ni ona jijin lati lo ki won to le fi okan awon obinrin balo lori awon eto won si ilera, imudogba eya ati isabiyamo ni alafia. Bi a ko tii le fi okan awon obinrin bale lori awon eto won ninu awon oran yi, bawo ni won se le toju omo ninu awon ipo lile bayi. Omode yio ni ilera yio si ni eko ti iya re ba ni ilera to si ni eko. Ilera awon abiyamo, ounje to peye ati eko se pataki fun iruula ati iwalalafia awon obinrin funrarawon, o si tun je okunfa pataki fun ilera ati iwalalafia omode nigbati o ba si wa ni ikoko.

O je ohun to dabi oro apara ni wipe bi edun-okan se wa kakiri lori aisi idagbasoke alagbero ni opolopo orile-ede ni agbaye, o dabi enipe awon olori ijoba, awon to nse eto imulo ati awon amoye lori idagbasoke ko riran ri anfani idoko-owo kansoso to je wipe o fun ni idaniloju ere. Eyi ni sise aridaju wipe awon omode ni ibere to dara ni aye won. Sugbon o se pataki wipe a gbodo mo wipe ayafi ti awon obinrin ba ni idaniloju igbe aye rere, awon omode ko ni ibere to dara ni aye. Laifa oro gun isopo ti o le daindain lo wa laarin iya ati omo. Ipo ti Awon Omode Agbaye wa ni Odun 2001 fojusi awon omode to wa lati ojo ibi si odun meta. Nitorina ohun to tona ni wipe ki iroyin na bojuwo alafia awon obirin ki won le bojuto awon omode doju aami. Lara awon ohun agbese fun ibere aye awon omode gbodo je lati se eto eko fun awon obirin ki won le mo nipa ise pataki ounje to dara ati itoju ilera nigba iloyun. Awon okunrin na gbodo gba igbeko lori ipa pataki ti won ni lati toju awon iyawo won aboyun ati awon omo to wa ninu won. Nipa ti awon omo awon iya ti a ju sewon, awon ijoba gbodo se agbekale itoju pataki fun awon aboyun ati awon iya ikoko ti a ti da lebi ite ofin won loju. Ni pataki, won gbodo ri daju wipe a ko ju iya sewon pelu omo re. Fifi agbara fun awon obinrin ma nyorisi imudarasi ninu igbe aye awon omode.
*All Africa.Com*

**Awon agelowo ati agelese nri ise ati iranlowo ni orile-ede Saro 11mins. 9secs.**

Awon olufaragba ninu ipolongo ajalu lati owo awon olote ni orile-ede Saro ni awon ajo kariaye ngba sise lati se iranwo ninu itoju awon opolopo asasala ogun to npada bo wa sile lati awon ibudo to wa ni awon agbegbe ti ko rogbo ni aala pelu orile-ede Guinea Awon agelowo tabi lese meta, okunrin meji ati obinrin kan, ni won nsise nibayi pelu Ajo kariaye fun Isikiri (International Organization for Migration (IOM) to se iranwo ninu pipade ati sise eto awon omo orile-ede Saro to npada bo si Freetown, olu-ilu.

Okan ninu won ni Mohamed Bah, omo odun medeoogbon, to bere ise ni osu to koja. Bah wa lati Koidu, ilu kan ni agbegbe Kono nitibi o ti figbakanri sise gegebi onidiri. Ni osu kerin odun 1998 aye e dara nigbati olote kan ti a ko damo fi ada ge owo re osi. O so lara itan re fun Chanzy, “Won ni mo gbodo jiya fun aiko ti won leyin. O dabi enipe won ti ya were, mo si sorire pupo lati wa laaye leyin ikolu na. Leyin ti won ti ge mi lowo, mo tiraka rin de ilu kan ti a npe ni Yengema, nibiti dokita kan to nsise fun Egbe Ogun Iwo-Oorun Ile Afirika fun Iseto alafia (ECOMOG) toju awon ogbe mi. Mo wa sa kuro ni agbegbe Kono mo si tedo si ibudo Waterloo fun awon to sipo pada ni ilu Freetown. Ni ojo kefa osu kini odun 1999, awon olote kolu olu-ilu na won si yinbo pa baba mi ninu ija na”. Fun opolopo osu Mohammed ti nwa ise sugbon nkan o rogbo. O ni “Yato si agbe sise, anfaani o po fun awon eniyan bi awa. Awa ti a ge lowo tabi lese ma nlero wipe a ko wulo. Nitorina ni nko se le gbagbo nigbati won wi fun mi pe mo le rise. Ohun to dara ni lati wulo ati lati ran agbegbe lowo. Pelu egberun Leone (Owo Dola Amerika Meje) ti mo ngba fun ise ojumo mo le se itoju awon aburo mi okunrin ati obinrin merin”.

Nigbati yio fi di arin meji osu kinni, ajo IOM ni Freetown ti gba Karatu Bangura. Obinrin yi, omo odun marundinlogoji to je iya omo meta nsise gegebi onisowo ni Kamaquay, ilu kan ni ibuso igba-din-mewa lati Freetown. Ni ojo kefa osu kesan odun 1998 awon olote ba pade nigbati o npada bo lati oja o si padanu apa re. Egbe Alagbelebu Pupa ti agbegbe na se eto lati gbe lo si Freetown. Ni akoko yi, oko Bangura ti

pada lo si Kamaquay lati ko lara eru won. Ko rii mo. Karatu si wa dawa pelu awon omo re keekeeke meta. Ni osu kini odun 1999 nigbati awon olote kolu Freetown, Karatu ni lati salo kuro ni orile-ede Saro lati wa aabo ni orile-ede Guinea to je alamulegbe won. Leyin eyi o pada si ilu ti a ti baje. Laipe o ba ara re ni ibudo to wa ni ilu Murray fun awon agelowo-lese.

O ni, "Aye sokunkun dudu. Ohun gbogbo su mi. O soro lati toju awon omo mi".

Ni ibere odun yi, Karatu gbo lati odo Egbe Alasia Pupa ti agbegbe na wipe ajo IOM ngba eniyan lati sise ni eti ebute. "Lakoko, mo ro wipe nko le ri ise na gba. Sugbon ore mi kan to nsise fun Egbe Alasia Pupa wumi lori lati bere fun ise na. Nitorina mo lo, o si ya mi lenu wipe ajo IOM gba mi. Ise mi ni lati ri daju wipe awon ebi to npada de nwa papo leyin ti won ba ti sokale lati inu oko" Ohun to je pataki fun Karatu nisisiyi ni lati fun awon omo re ni eko to dara. Inu re dun wipe won fi ise yi tan an. On ni agelowo-lese obirin ti ajo kariaye kan yio gba sise.
Titi di idaji osu to koja ibudo ilu Murray je ibugbe fun awon agelowo-gelese bi odunrun ati ogbon pelu awon ebi won. Awon olufaragba ipolongo ajalu na si npada bo, bi otile je pe iye won ti nkere sii.
*IOM*

**Iyipada Afefe Ile yio na ni lowo toto Odunrun Bilionu Ow0 Dola Amerika Lodoodun** **6mins. 16secs.**

O seese ki imorusi aye ni agbaye na ni opolopo bilionu owo dola Amerika lodoodun ayafi ti a ba gbe igbese ni kiakia lati dekun itujade efin oloro CO2 ati awon eefin alagbara miran to nba ayika je, gegebi iroyin kan se so. Iroyin na lati owo awon adojutofo ati omo egbe eto imusese lori oran isuna ti Ajo Agbaye fun Eto Ayika (UN. Environment Programme (UNEP) tokasi wipe awon adanu to nwaye latari iji lile alajayika to nja nigbagbogbo ju ti ateyinwa lo, ipadanu ile latari giga ti ipele okun nga sii ati ibaje awon akojopo eja, ise-ogbin ati ipese omi le na ni ni owo to to oodunrun bilionu (milionu lona egberun) o le irinwo milionu ati igba egberun owo dola Amerika lodoodun.

Gegebi iroyin na se woye, ni awon orile-ede to wa nibi petele bi Maldives, awon Erekusu Marshall ati awon apapo ipinle Micronesia, awon adanu to sopo mo iyipada afefe ile le ju idamewa gbogbo oro orile-ede won tabi owo gbogbo to nwole labele lo nigbati yio ba fi di odun 2050. Nigbati o nsoro lori iroyin na, Klaus Toepfer, Oludari Alase fun ajo UNEP so wipe. "Akoko lati sise niyi. Gbogbo wa gbodo sise lati din itujade awon eefin alagbara to nba ayika je ku". Sugbon o woye wipe idinku nikan ko to. Aye ti fekan juwo si iwe fun iyipada afefe-ile lati owo eda eniyan de ipele kan latari awon itujade fun akoko to ti ju orundun kan lo lati awon ile-ise ise-nkanjade, paapa lati iha aye to ti dagbasoke.

Toepfer so wipe iroyin to sese jade lati odo Ajo onijobasijoba lori Iyipada Afefe Ile (Inter-governmental Panel on Climate Change (IPCC) eyiti ajo UNEP ati Ajo Awon Awojuojo ni Agbaye (World Unetorological Organisation (WMO) jijo se onigbowo re na ti tenumo idi fun imusese ni kiakia. Ajo na, ninu eyiti a ti ri egbegberun awon onimo ijinle sayensi lati kakiri aye, gbagbo wipe iwontunwonsi igbona tutu jakejado aye le lo soke lati ipele centigrade kan ati iko merin ninu mewa eyo kan si ipele marun ati ikomejo ninu mewa eyo kan laarin orundun to nbo yi.

Toepfer ni "A gbodo tesiwaju pelu igboya pelu awon imo-ero mimo, a si gbodo bere si gba ara wa di nisisiyi fun ilosoke ipele omi okun, iyipada ninu awon ilana ojo ati awon ikolu imorusi aye miran". O tun so siwaju wipe o se koko fun awon orile-ede lati tun bere awon apero lori iyipada afefe ile to ni idaduro ni Hague ni opin odun 2000 ki awon orile-ede le gbe awon igbese akoko lati funni ni awon idinku itujade to ni laari.
*Pan African News Agency*

**Iyipada Rere ati Awon Ajo Iroyin** **4mins. 50secs.**

Kabral Blay-Amihere to je Aare Egbe Awon Onise Iroyin ni Iwo-oorun Afirika (West African Journalists Association (WAJA) ti kilo fun awon onise iroyin wipe ki won mase jeki ifitorese nipa lori ibalopo won pelu ijoba. O ni niwongba ti awon onise iroyin ba se atileyin fun igbese laarin orile-ede fun iyipada, won ko ni ribi sapamo si ti ijoba tuntun na ba kuna lati mu iyipada rere to seleri wa saye. Ogbeni Blay-Amihere nso oro akoso pataki lori koko oro "Iyipada Rere ati Awon Ajo Iroyin" ninu ipade gbogboogbo olodoodun ti Egbe Awon Onise Iroyin ni orile-ede Ghana (Ghana Journalists Association (GJA) ni ilu Accra ninu eyiti a ti se ibura fun igbimo alase eleni meje ti yio sise fun odun meji.

Aare WAFA na so wipe: "A gbodo jeki ijoba mo wipe agbara ti awon eniyan fun won ki ise ipe si ayeye tii mimu" o ni awon onise iroyin gbodo yera fun iwojureyinni ki won ma ba ba iwulo won je gegebi aja-ode fun awujo. Ogbeni Blay-Amihere seleri iranlowo egbe GJA fun ijoba Aare Kufuor "ti o ba nfun awon ajo iroyin ni ifitonileti, to ba pa ofin lori iwa odaran akosile ibanilorukoje re ti o si se ofin ominira fun ifitonileti". Iyaafin Gifty Affenyi-Dadzie to je Aare Egbe GJA so wipe alekun imo awon ara ilu lori agbara awon ajo iroyin gbodo gun awon onise iroyin ni kese lati tubo se aseyori to ga sii. "A gbodo sora fun itelorun-soni-dole ki a si ma ja fitafita fun itayo nipa gbigbe asia iwa omoluabi ise wa soke". Iyaafin Affenyi-Dadzie so wipe Egbe GJA yio gbe eto iwoye kan kale lati ma topase awon iwa to lodi si iwa omoluabi.

Egbe GJA je okan ninu awon egbe iwo-oorun ile Afirika merin to je anfaani awon ise ise-idiwon-ara eni eyiti Ajo Alasepo ni kariaye fun Awon Onise Iroyin (International Federation of Journalists) nse onigbowo re pelu owo lati owo Ajo Apapo Ile Europe.

*Accra Mail*

**Awon ti a da lola Nobel soro lori Ominira Ise Iroyin** **3mins. 16secs.**

Awon meji ti a da lola Nobel, olori ile Tibet nipa ti emi, Dalai Lama ati Bharat Ratan Amartya Sen, ti ro ise iroyin lati lo ominira re lati se iyipada awujo ki won si se ifojusi ero tooro to si nse idiwo fun aye lati di abule kansoso. Awon mejeji ba ipade ikeji ti Apejo Agbaye ati Ipade Gbogboogbo Aadota ti Ile-ise Ise Iroyin ni Kariaye (International Press Institute).

Dalai Lama na woye wipe aye ti gberalerawon pupo sugbon okan eniyan ni 'ero atijo' si ndari re. O ni ise iroyin le lo ominira re lati mu ki irepo ga si laarin awon eniyan. Ogbeni Sen nitire so wipe ominira ise iroyin gbodo je eyiti ko ni ayafi biotilejepe awon ewu bi isi-oro-eniyan-so ati iyawonu-ibi-ikoko-eni wa. O ni ise iroyin olominira gbodo se aridaju ominira oro eni fun gbogbo eniyan. O ni ninu ijoba tiwantiwa o ni agbara lati se idena ajalu bi iyan.

Dalai Lama so wipe eko ko le gbile laisi ise iroyin olominira. O ni ise iroyin ni eto lati wadi awon olori esun, awon oloselu ati awon ti a da lola Nobel paapa.

*The Independent (Banjul)*

**Ajo Agbaye yan Rawlings latari Ikun-oju-iwon** **5mins. 39secs.**

Sharon Capeling-Alakija, Oludari Alase ti Awon Ayonda-araeni funse ti Ajo Agbaye (UN Volunteers (UNV), so wipe Aare orile-ede Ghana tele, Jerry Rawlings ni won yan gegebi Eniyan Pataki Ajo Agbaye fun Iyonda-ara-eni-funse latari ikun-oju-iwon ati ifaraji re to jinle si awon oran ilera to se koko. Osise Ajo Agbaye na so ninu apejo ifitonileti kan fun awon oniroyin ni ilu Accra wipe: A tun ro wipe a nilo ogboju ati olooto onsoro gegebi Rawlings lati so fun awon eniyan iru awon iwa ti won ni lati mu kuro ki won le yera fun ako iba ati ikolu kokoro-arun HIV ati Arun kogboogun Eedi, Rawlings fi edun-okan to jinle han lori ako iba ni pataki. O si tun ti bo ajaga ise isejoba sile, nitorina o ni aaye lati se ise ti a fi fun.

O se alaye wipe ipa ti a fun Rawlings gegebi Eniyan Pataki ki ise igbanisise lati owo Ajo Agbaye sugbon anfaani kan ni fun lati tesiwaju ninu igbejako re si awon arun apani bi Arun Kogboogun Eedi ati ako iba ni ipo iyonda-ara-eni sugbon ni ona to gbooro sii. Iyaafin Capeling-Alakija so wipe "pelu iriri re gegebi aare

tele ati ajafitafita ni idojuko awon arun ni orile-ede re, a gbagbo wipe ilowosi re yio mu awon akitiyan wa le si ni ikoju awon arun apani mejeji yi". O tesiwaju wipe ninu ipo re titun, Rawlings yio se asiwaju ninu awon akitiyan ajo UNV ni igbejako Arun Kogboogun Eedi ati ako iba ni ile Afirika labe eto ise pataki, pelu afikun wipe ojuse re yio tan lo si awon ekun aye miran labe eto Ajo UNAIDS kan. O ni olori orile-ede Ghana tele na bere ise ni owuro ojo aje, ojo karun osu keji, yio si tesiwaju titi di opin odun yi nigbati yio ni aaye lati se atunse ifaramo re tabi beko. Osise Ajo Agbaye na fikun wipe "Ni ipo re laipe Rawlings yio bere eto kan ninu eyiti yio ti ma ba awon apero kariaye ati awon awujo agbegbe soro loni bawo ni a se le koju Arun Kogboogun Eedi ati ako iba lona to munadoko".

*Pan African News Agency*

**Itoju Ayika lo sinu Fiimu** **6mins. 27secs.**

Ijakadi lati se imubadogba aisiki eda eniyan ati itoju eda abemi egan ni o je ipilese fiimu ti oludari fiimu omo-bibi orile-ede South Africa, Elaine Prector sese se. 'Kin' topinpin itakorawon to wa laarin itoju ati awon eti agbegbe, o si tun se ayewo imuwalalafia awon eya pelu ara won ni orile-ede Nambia loni. Fiimu na so itan Anna, odomode olutoju awon eda abemi egan kan to ngbe ni ekun Nambia kan to jinna rere. Pelu arakunrin re, Marius, Anna ja lati gba akojopo kekere ti awon erin kan to ma nmumi lalaale ninu kanga re la. Fun Anna ati Marius awon erin na lo je ibatan dipo awon eya Himba ti itedo won wa legbe oko won, ti ihuwasi Anna ati arakunrin re nyalenu. Sinu igbesi aye Anna to jinna si awujo ni Stone omo ile Afrika kan to ngbe orile-ede Amerika, to si wa sise fun igba die ni orile-ede na, gbese wole. Pelu mimu omo Himba kan ni agbegbe na fun ijiodese, eniti opolopo awon eniyan agbegbe ro wipe ko jebi, lojiji aye Anna jasi inu okun idaru dapo, ninu ipo to ti soro lati ri idahun kokan.

Gegebi Proctor se so, "okunfa fun iyipada iriri Anna ni ife to ni fun alejo to wa lati ode to si ran an lowo lati da ohun gbogbo mo".

A le ri 'Kin' ni opolopo ona gegebi iranpo fun eto ibalaja. Ona eyiti orile-ede na si nsise ginniginni pelu irora lati la koja.

Proctor fe ki fiimu na ni imolara fiimu agbegbe nitorina ni o se lo opolopo awon eniyan ibile lara eyiti awon omo eya Himba wa ki won le gbe ara won yo. Igbe ara won yo ni idojuko awon oran ti won ntiraka ni lowolowo lati wa ojuutu si ni o fun 'Kin' ni emi otito re.

Fiimu na da awon oran oloselu po mo awon itan to takoko ni ona to dara lati se ifojusi awon itakorawon to wa lode oni ni iha gusu ile Afirika. O pari sa pelu igbagbo wipe ohun gbogbo yo dara. Kin tanmo wipe kiise wipe eda eniyan le wa ona lati gbe ni ibamu pelu iseda aye nikan, sugbon, boya, ju eyi lo, a tun le ko lati gbe pelu eda eniyan elegbe re.

*IPS*

**Leyin Awon Omode Na** **3mins. 29secs.**

Awon asoju Ile-ise Ajo Agbaye fun Awon Asasala Ogun (United Nations High Commission for Refugees (UNHCR) ati Ajo Alasepo lori Akojo Owo fun Igbala Awon Omode (Save the Children Fund) ti gbe iroyin kan jade lori eto ise kan lati koju oran awon omode it a ko sile to nwa ibugbe ni ile Europe. Iroyin na se agbeyewo bi nkan se wa ninu awon orile-ede meedogun ti ajo Apapo Europe ati Norway, o si wa se agbekale awon imoran fun ise ni ipele ti ile Europe ati ti orile-ede kokan. O kaju awon omode ati awon odo ti ojo ori won din si odun mejidinlogun to ngbe leyin odi orile-ede abinibi won laisi obi, ibatan tabi enikeni ti yio ran won lowo, to si je wipe, ni opolopo igba, won ti sa kuro ni orile-ede won lati jajabo kuro lowo inunibini, iteloju eto eda eniyan, rogbodiyan ologun ati aisi aabo ni gbogbo ona, ikokiri fun ilonilokulo nipa ibalopo, tabi osi to le pupo.

Gegebi ajo UNHCR se so, awon omo ti a ko sile yi to nwa ibugbe ko ni aabo labe ofin tabi itoju to peye. Ni ipele ti ile Europe, awon oran yi ko ri amojuto yala nipa ti ofin tabi ilana imulo besi ni ipile fun ise sise ni agbegbe yi gbelege. Nitori idi eyi ni iroyin na se nparowa fun agbekale ati imulo awon eto imulo to tona ninu ajo Apapo Ile Europe ati ni awon orile-ede omo egbe.

*The Courier*

**Ilo si ipo fun Ile Afirika ninu Igbimo Aabo Ajo Agbaye? 8mins. 22secs.**

Biotilejepe Apejo Egberun odun ti yio wonu iwe itan ti o waye laarin ojo kefa ati ikojo osu kesan odun 200 fojusi isoro osi ni agbaye ni pataki, aye tun wa fun ifikunlukun lori atunse to jinle ninu Ajo Agbaye lati mu wa ni ibamu pelu aye to nyi pada ki o si di irinse to munadoko fun iko-bi-ara-si ifojusona orisirisi awon orile-ede. Bi o se sese gba omo-egbe re ogosan ati mesan wole pelu dide Tuvalu, ajo na ni lati se atunse ninu awon ohun imulo re fun ise-ipinnu gegebi iroyin na ti Lakhdar Brahimi to ti figbakanri je minisita orile-ede Algeria fun oro ile okeere gbekale fun Ajo Agbaye se so. Iroyin yi, ti awon olori orile-ede fi owo si awon isori-isori re, ni o si ariyanjiyan lori mimu Igbimo Aabo to nse kokari imuwalalafia gbooro si.

Nipa bibere fun ipo fun Ile Afirika lori igbimo yi, awon olori ile yi nireti lati se alekun ipa re ninu Ajo Agbaye, ko si si owon ariyanjiyan ni isegbe fun iru igbese be. Ni odun 1945, nigbati a da Ajo Agbaye na sile, iko meji ninu meta awon omo-egbe re loni ni ko wa gegebi orile-ede olominira, gbogbo olugbe aye nigbana si je bilionu meji ati aabo pere. Loni o wa ni ekun bilionu mefa. Ile Afirika nikan ni awon olugbe edegberin milionu, lara won ni a si ti ri awon orile-ede metalelaadota ninu orile-ede ogosan o le mesan to je omo egbe ajo na. O ju idameta awon oro ti igbimo yi ngbe so lo to kan ile Afirika gbongbon. Awon miran ni ero wipe ilana ise-ipinnu tooro yi gbodo yipada lati se afihan iru isojueni titun to wa ni ogboogba. Bawo ati lati owo tani a o se se isojueni ti ile Afirika yi nigbati a ba jaja gba aba na wole? Ibeere yi, gegebi awon asoju ile Afirika se fi tayotayo kede, ko gbodo mu isoro pupo wa. Boya Ajo Apapo Ile Afirika to waye ninu Apejo ti Ajo OAU ni osu keje odun to koja, yio fun ile Afirika ni ipa to po si ni Kariaye?

Awon olori orile-ede na tun soro lori imulagbarasi awon oro ajo Agbaye lori isuna, ologun ati eto ise lati jeki ajo na le se awon ise re ni aseyori, paapa awon ise imuwalalafia re. Opolopo ipade ni won tun se, ti won si se ibasoro olorile-ede-sori leede pelu orisirisi awon olori orile-ede ni ode Apejo na ninu itiraka lati wa ojuutu si awon isoro pataki kan. Bi awon ipade na se nlo si opin, ibere kan duro lori ete gbogbo eniyan. Nje awon ipinnu rere ti a ko sile ninu Ikede ti Apejo Egberun Odun na ni a o mu lo? Ohukohun yio wu ko sele, bi opolopo iru ipade yi se ma nje, awon ipinnu yi yio da pupo lori ife-ninu oloselu ti awon to se won.

*The Courier*

# *Bi mo se ri si*

**Idajo Ododo fun Awon Omode Orile-ede Saro 10mins. 40secs.**

Igbimo Ajo Agbaye to nse iwadi lori ipa ti orile-ede Liberia ko ninu egbe alafowosowopo lori pasipaaro okuta iyebiye dayamondi fun ibon, eyiti o nfa iha iwo-oorun Ile Afirika ya, ti pari ise re. Orile-ede Liberia ti Charles Taylor ni orisun awon ipaya. Ijewo yi ati awon ise agbese ti won tanmo dabi ebun keresimesi lati odo eda aye to mu ise re lokunkundun si awon omode ati eniyan orile-ede Saro. Igbimo na, laarin awon miran, fe ki a gbesele irin-ajo ofurufu ati irinajo miran fun ijoba orile-ede Liberia. O nfe igbesele lori awon okuta oniyebiye dayamondi to nbo lati orile-ede Liberia. O tun nfe ki a gbesele gedu re. Awon igbese yi ni a gbagbo wipe yio fi aami to lagbara ranse si awon odaran to wa ni orile-ede Liberia wipe opin won lati ma lo iselu fun awon nkan ifojusi ti ko bofin mu ti de tan.

Awon awari ati aba igbimo na lo wa lara awon igbese akin taara ti o waye lati igbati Charles Taylor, pelu atileyin orile-Libya, Cote D'Ivoire, Burkina Fasso ati awon odaran abele ni kariaye ti bere ilana fifo iwo-oorun ile Afirika si wewe labe ibori awon ibeere oloselu. Boya ti a ba ti gbe awon igbese yi ni odun mewa seyin, awon egbegberun lona mewa omode lati orile-ede Liberia, Saro ati nisisiyi, Guinea, iba ti ruula. Sugbon a gbagbo wipe akoko ko iti pe ju lati ya ijera to nfi aso boju bi ijoba tiwantiwa yi soto. A gbe oriyin fun igbimo na.

Fun akoko to koja ewadun, awon akitiyan oro aje ni orile-ede Liberia ati Saro ni o ti duro patapata. Awon agbe ti ni lati fi awon abule won sile ki won si wa ibugbe labe ago lati ma je onje awon oninure. Oga patapata ti ajo UNCHR to nlo, Iyaafin Sadako Ogata, ti woye wipe laiko se agbekale awon ohun ti a nilo fun lilo kuro ni ipo pajawiri si igbokanle-ara-eni, awon ogun ati isoro na yio ga sii. Otito ni wipe igbekale iru awon ipo be rekoja ipa awon ijoba to wa lori aleefa ni ile Afirika nisisiyi, opolopo ninu awon ti igbimo Ajo Agbaye na daruko gegebi olugbowo. Lati reti wipe won o gbe awon igbese to ye lati gba awon eniyan na la ni ilodisi ife-inu ti ara won je ala ibanuje. Idi niyi ti awujo kariaye, isoro yiowu to le wa nibe, di ireti nla kansoso na.

Awon to njiyan ni tako itilekunmo fun awon 'adete' buruku wonyi, nipa lilo ariyanjiyan ayebaye wipe itilekunmo yio se jamba fun awon eniyan ilu, gbodo wo orile-ede Liberia Taylor bi on funrarare se lowo to ti orile-ede re ko si ni. Ile-iwosan kansoso to wa lorile-ede na ni won ti ti pa. Awon onisegun meedogbon pere lo si wa fun gbogbo ise ilera ni ifiwe si irinwo ki idibo to waye. Ise ijoba, nibiti o ba si wa, ti pada si akoko igba ki awon olujegaba to de. Fun apeere, Ile-ise fun Isuna ko ni oko irinna, nitorina ko le se aridaju owo osu sisan fun awon osise to wa leyin odi olu-ilu Monrovia. Bi awon osise to wa ni olu-ilu tile ni iwe sowedowo won lowo, ko si owo ni awon ile ifowopamo si nibiti won o ti le gbowo jade. Nigbeyingbeyin won a ma se pasipaaro iwe sowedowo na fun awon onipasiparo owo loju titi ni edinku to ga. Gbogbo eyi nsele labe okunrin to seleri wipe on yio lo owo dola Amerika gegebi owonna ni orile-ede Liberia, ti o si seleri fun gbogbo omode lati fun okookan won ni ero asisebiopolo Komputa bi ko tile si ina ilentriki, omi tabi aga ijoko ati bebelo fun awon ile-eko. Ju eyi, eniyan kan le bi awon omode orile-ede Saro ni itumo ijiya nitori ijiya wo lo tun le ga ju didu omo odun marun ni awon apa tabi ese re ni oruko awujo rere - ipinnu egbe RUF ti Taylor. Awon awari ati ipinnu igbimo ajo Agbaye na, ti a ba mu won lo ni gbogbo ona, lo fun awon omode orile-ede Saro ni akoko lati rerin. A lero wipe a o lo awon awari na. Inu wa dun rekoja.

*A gee ku lati inu Oro Olootu inu iwe iroyin The Perspective*

# *A ti gbo*

**Orile-ede Algeria gba awon Ile Olomi titun** **2mins. 33secs.**

Orile-ede Algeria ti se akosile awon ile olomi titun mewa to se pataki kariaye ni isaami Ojo Ile Olomi ni Agbaye eyiti o waye ni ojo keji osu keji odun yi, gegebi iroyin se roo ni ile Algiers. Lara opo awon ibudo na ninu asale ni iha gusu orile-ede na, ni a ti ri Afonifoji Iherir (ekun Illizi), Ile Abata Gueltates ti Isskarassene (Tamanraset), Chott Meronane, Qued. Khrouf (El-Qued), Ould Said Oasises, ati Tamentite ati Sid Ahmed Timmi (Adrar). Nisisiyi, Algeria ni ile olomi metala ti o nipo Kariaye ti o si gba ile lati sare hektari edegbaata si eyi to ju milionu kan ati egberun lona egberin o le mokanlelogota sare hektari, tabi iye kanna si gbogbo oju ile olomi ni orile-ede Amerika, gegebi isiro awon osise Ajo Akojo owo ni Agbaye fun Iseda Aye.

Ojo Olomi ni Agbaye ni a saami re ni Algiers pelu fifi iwe eri fun awon ile olomi mewewa fun orile-ede Algeria.

*All Africa.com*

**Omodekunrin kan to nsaisan lile latari Arun Kogboogun Eedi di omo odun mejila** **3mins. 6secs.**

Bi ajafitafita lori oran Arun Kogboogun Eedi, Nkosi Johnson se sese di omo odun mejila, ko si idi fun ayeye. Omodekunrin na, to ti wonu okan awon milionu milionu eniyan kakiri aye, ni o nsaisan lile ni ile re ni ilu Johannesburg laisi idarasi kokan ninu ipo re. Nkosi ti a bi pelu aami kokoro-arun HIV ni o subu lule ni osu kejila odun to koja latari ibaje opolo to jemo arun Kogboogun Eedi ati ikolu awon kokoro-arun.

Awon eniyan bi igba, lara awon ti a ti ri awon omo orukan Arun Kogboogun Eedi ati awon eniyan to ngbe pelu kokoro-arun HIV ati Arun Kogboogun Eedi ni won wa si ayeye kan ti a se fun Nkosi ni ile-eko Alakobere ti Melpark ni Melville nibiti o ti ka iwe kerin ni odun to koja. Ninu ile eko yi kanna ni omode na ni odun 1997 ti koko wa si ifojusi awon ara ilu nigbati awon obi tiraka lati dena igbawole re nitori ipo re gegebi eniti o ni kokoro-arun HIV ati Arun Kogboogun Eedi.

A ranti Nkosi julo fun gigori itage ni sisi Apero agbaye to tobi ju lori Arun Kogboogun Eedi ni ilu Durban ni odun to koja ti o si kepe Aare orile-ede South Africa, Thabo Mbeki lati fi aaye gba egbogi agbejako-Eedi ti a mo si AZT fun awon aboyun.

*Africa Online*

# *Eto Awon Omode*

**Kumbo ati Mhisi** **12mins. 7secs.**

Nigbakan okunrin kan wa, on ati iyawo re, ti won ti gbe fun opolopo odun ni abule kan pelu omo won, Kumbo. Ni akoko itan yi, awon obi na pinnu wipe o to akoko lati si lo si abule miran, nitori won ti gbe ninu ile won atijo pe to. Won soro lori igbese yi pelu omo won kansoso, enu si ya won nigbati o wipe: “O ti o, eyin obi mi. Eyin le lo sugbon emi ki yio lo. Mi o ri idi ti e fi fe fi ile to dara bayi sile.”
“Sugbon, omo mi,” iya re dahun, “a le ko ile miran to tura bi eleyi furara wa laisi wahala.” “O ti o” omo olorikunkun na taku... “Bi eyin ba tile lo, emi yio duro nihin.”

Awon obi na ti pinnu lokan won. Ile won atijo ti su won won si fe kuro. Omo na si ti pinnu lokan re. Inu re dun nibiti o gbe wa, o si ti ko lati lo. Nitorina won fohun sokan lati pinya. Awon obi na ko eru won lo si abule titun nigbati Kumbo da nikan duro si ile atijo na.

Ile titun awon obi na ko jinna, nigbati o si di irole ojo na gangan, iya pada wa sodo Kumbo o si wipe: “Nko le jeki ebi pa omo mi kansoso nitori a ti si lo, nitorina ngo ma gbe ounje re wa lojoojumo. Wa mo wipe emi ni mo de nigbati o ba gbo ti mo korin bayi:

‘Ni-vi-yi Kumbo
Ni-vi-yi Kumbo
Se Kumbo niyen?’

Eto ti won se niyi, iya na si npada wa lojoojumo lati fun Kumbo ni ounje. Ni ojo kan, Mhisi, akata, to nsinmi ninu igbo nitosi, ri nkan to sele, o si gbo orin na.

“Ah-ha:, o wi fun ara re, On ti mo ni lati se ni lati ko orin na ki nle ni omo na fun ara mi nikan lati se ohun to ba wu mi pelu re .. dajudaju wo si mo ohun ti mo fe lati se pelu okele adidun bayen.”

Leyin ti iya ti lo, Mhisi lo si ile na o si korin leyin ilekun.

'Ni-vi-yi Kumbo
Ni-vi-yi Kumbo
Se Kumbo niyen?'

Ninu ile omokunrin na sun sori eni re, o si wa mo wipe ohun yen ki ise ti iya on. Paapa, iya re sesee mu ounje re wa ni ojo na ikun re si kun. Nitorina o dake titi ti Mhisi fi jawo ti o si lo.

Ni ojo keji nkan kanna sele, omodekunrin na si kigbe "O nfi akoko ara re sofo, eni yio wu koo je. Mo mo wipe o kiise iya mi, nitorina nko ni jeki o wole.

Mhisi yo gologolo lo sinu igbo o si wa bere si rori ona lati fi wonu ahere na.

Ni ojo keji o de saaju iya Kumbo, o si wa korin na bi o se le koo dun to.

'Ni-vi-yi Kumbo
Ni-vi-yi Kumbo
Se Kumbo niyen?'

Nisisiyi, Kumbo nreti iya re ni akoko na, ebi si npa gidigidi. Ka so otito, ninu ikanju re lati jeun, o ti gbagbe eda to ti ngbiyanju fun bi ojo meta lati wonu ile na. Nitorina o fo soke o si si ilekun.

Mhisi gba apa re mu o si wo lo.
"O Akata," omokunrin na kigbe pelu eru. "Nibo ni a nlo? Mo ndurode iya mi lati mu ounje wa. Yio de laipe."

'Ma foya Kumbo," Mhisi dahun. "Iya re lo ran mi wa sibi. On lo ni ki nlo mu o wa."
Nitorina ifoya Kumbo role, o si dake bi Mhisi se gbe lo sinu igbo to jin. Nigbana, ki Kumbo to mo ohun to nsele, Mhisi paa o si jee.

Kumbo ode! Se o ro wipe omode lemo ju awon obi re lo ki o si tako ipinnu won?
*Shangani Folk Tales*

# *Oro Asokagba*

Awon oro manigbagbe lati owo awon olori Ile Afirika.

Lori idagbasoke
*Aini idagbasoke to to je irokeke ewu to tobi julo si alafia. Ohun aigbodomase wa kinni ni lati pa osi, ainimo ati arun run, ki a si se agbekale awon ona orisirisi ti olukuluku eniyan le gba lati gberu, lori anfaani olokan-oju-okan fun okunrin ati obirin.*
Sam Nujoma
*Aare orile-ede Namibia ninu Apejo Egberun Odun.*

Lori Ilujarawon-aye
*Ti a ba fe gba awon anfaani ilujarawon-aye mu ki a si dena awon ikolu ti ko dara ninu re ni igba kanna, nigbana a gbodo ko lati se ijoba to dara si ki a si se ijoba papo.*
Kofi Anan
*Akowe Agba Ajo Agbaye ninu Apejo Egberun Odun.*

Lori Rogbodiyan
*Eniti o ba sun lebi yio ji pelu okan to kun fun ikorira.*
Pierre Buyoya
*Aare orile-ede Burundi ninu Apejo Egberun Odun.*

Lori Eko
*Eko ki ise ona lati fi jajabo kuro ninu osi orile-ede sugbon ona lati fi gbejako o.*
Julius Nyerere
*Ologbe Aare orile-ede Tanzania.*

Si ranti.........
*Ewa ma nwa ju ohun gbogbo lo, lati inu okan, lati inu ilera okan ati ipeye eniyan funrarare.*
Nawal El Sadaawai
*Onkowe: Oju Eefa ti o pamo.*